# ELETI OFE

A-NJU-WON KO ṢE WI LEJO...

VOL. XIV NO 825 LAGOS SATURDAY JUNE 23, — JUNE 29, 1962. KOBO MEJI(2D)


OKUNRIN KAN

# Akosi B'ero Bu'na Si Aropleni

## NITORI OWO

AMẸRIKA—Ododo ọrọ ni adura ti ọpọlọpọ enia nma gba wipe Ọlọrun ma jẹ ki a rin lọjọ ti ebi npa ọna, sugbọn adura yi ko ṣẹ rara fun awọn ero mẹrinlelogoji alawọ-funfun ti nwọn wọ ọkọ ofurufu (aeroplane) ni idi'kọ ofurufn kan ni ilu Amẹrika ninu oṣu ti o kọja. Ko pẹ ti ọkọ aropleni na gbera nilẹ ti o nlọ ni ofurufu loju ṣonmọ ni o gbina ti o sị la si meji, ti gbogbo awọn ero inu rẹ ku patapata lai da ẹnikan si.

Onirohin wa fi ye wa wipe jamba ọkọ ofurufu yi kiṣe oju lasan. Ọgbẹni kan ti ọrukọ re njẹ Thomas Doty, ẹni ọdun mẹ'alelogbọn, ni o fa sababi, o ni owo ko 'ọwọ on, o ni kaka ki on lọ ba nwọn fọle ni oru, ki on kuku pa ara on, ki on fi owo silẹ fun awọn ẹbi on ki nwọn ri nkan fi jaiye.

Ni ọjọ ti o fẹ wọ'kọ yi, o lọ si ọdọ awọn ẹgbẹ onisowo ti nwọn nsan owo lori ẹmi tabi nkan ti • ba s'ofo (Insurance Company) wipe oku ati aye on to ọkẹ marun-o-le-ẹdẹgbarin pọnun (£107,000) nitorina on fẹ lati san owo fun adehun silẹ ki nwọn le san iye owo yi fun iyawo on ti on ba ku ninu ọkọ ofurufu ti o mba lọ si idalẹ na. O si di nkan jamba ti o le mu ọkọ ofurufu na gbina sinu ẹru rẹ; eyi ni o mu ki ọkọ aropleni na fọ yẹlẹ-yẹlẹ, ti o si pa gbogbo awọn ero inu rẹ ati on alara paapa.

Isalẹ ọrọ l'ẹgbin.

# Egbe Alamojuto Ire Eko Se Ipade

## Bi Eko Yio Se Toro Ti Y'oroju

EKO – Ni ọjọ Ẹti (Jimọ) ḷjẹsan ni awọn ọmọ Ẹgbẹ Alamojuto Ire ilu Eko (Lagos Citizen's Rights Protection Council) tun ṣe ipade nla kan ninu ile-iworan sinima Corona ni ita Faji ni dede agogo mẹrin abọ ni irọlẹ. Ẹniti o ṣe alaga ọjọ na ni Ọgbẹni F. Olu. Akapo, awọn isọngbe rẹ si ni Oloye Adebayọ Doherty (Baba Ẹgbẹ na), Ọgbẹni A.T. Ariyọri (Akọwe Ẹgbẹ), Oloye Abudu Kafari, Eletu Odibo, Oloye Abudu Wahabi Balogun, Lẹmọmu H. A. Yesufu Ogunro, Lemọmu Alhaji Ẹtti ati Iyafin (Oloye) Amọri Adeọba, Eletu Iwasẹ.

Lẹhin ti Alaga ti kesi Lemọmu Ogunro wipe ki o ba awọn fi adura ṣi ipade na, ni Alaga paapa wa bẹrẹsi pe awọn oguana gbongbo inu ẹgbẹ na lati maṣe alaye kinni ẹgbẹ na wa fun, ati pe kini fa sababi ti awọn ṣe da a silẹ. Olukulu awọn ti o sọrọ na si ṣe alaye wọn na yepe-yepe.

Inu gbogbo awọn alejo ti o wa si awujọ na si dun lati gbọ alaye yi, tobẹgẹ ti ọpọlọpọ wọn fi fi orukọ silẹ lati di ọmọ ẹgbẹ na.

Alaga ipade na ninu ọrọ rẹ ti fun fi ye gbogbo apejọ na bi inu awọn ti dun to lati ri Alufa (Rev.) J. O. Shonayo, ẹniti o fi ile ati ọna rẹ silẹ ti o wa jẹ ipe ẹgbẹ awọn lati Ibadan. Nwọn si fi tayọ tayọ ki Ẹni-owọ na ku abọ, o n paapa si ba wọn sọrọ iṣiri.

Ninu ọrọ rẹ, Alufa Shonaya ni inu on dun lati gbọ irohin akitiyan ti awọn oguna-gbongbo inu ẹgbẹ yi nṣe lati le ri wipe ẹgbẹ na fidi mulẹ. O ni gbogbo ilu ti awọn nlọ ni ilu Okere jake jado ni awọn nri bi awọn ara ilu nwọnyi ti nsa agbara lati ri wipe iya ko jẹ awọn ati ọmọ ti awọn bi.

O ni o to gẹẹ, akoko to o si yẹ fun awọn ọmọ Eko ki awọn na ṣe eto lati kọ iya fun ara wọn; ko si akọya kan nibi kan, ọwọ ara wa ni a ni lati fi tun nkan wa ṣe.

# Awo Irawo

**Eyi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.**

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Lati ojo Aje lo ni wa ti bẹrẹsi daraya ti i nse yio fi dele.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Awọn ti o wa labẹ rẹ ti o ti fi aye gba a fun o ni iwọnu die.

ARIES (Mar 21-April20) Aṣẹ pajawiri kan le jade, gbogbo ẹniti wọn ba jẹ mọ t'ọlọpa tabi ṣoja a ri ilọsiwaju.

TAURUS (April 21-May 20) Iṣẹ ti o se ni ọsẹ ti o kọja, a jẹ ki o rọ die ninu ọsẹ yi.

GEMINI (May 21-June 21) Ni ojo Aje wa ri iran kayefi lorişirişi sugbọn ko ni kan ẹ lọwọ tabi lẹsẹ.

CANCER (Jun 22-July 23) Ti o ba ṣọra pẹlu a nnu yi, a nnu to'hun, wa ko wahala ba ara rẹ.

LEO (July 24-Aug 22) Ẹda ti Ọlọrun da ẹ, a jẹ ki o hu iwa iyalẹnu fun awọn ti nwọn lero wipe awọn mọ iwa-inu rẹ daradara.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) I w ọ paapa a le ba awọn ẹlẹnu dundun jiyan ọrọ pọ larin ọsẹ yi.

LIBRA (Sep 24 -Oct 23) Ọ j ọ mẹta ni wọn a jẹ patiki fun ọ ninu ọsẹ yi, awọn ọjọ na ni Alamisi, Jimọ ati Satide.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ṣọra mase fi agbara rẹ ati owo sofo rara. Ẹnikan a jẹ ki o binu pupọ lọjọ ọsẹ (Sunday) ibinu na a si wọ ẹ lọkan pupọ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Ṣọra pupọ lọjọ Aje ti mbọ yi, nitoripe ọjọ na lewu fun ọ.

CAPRISCORN (Dec 23-Jan 21) Iwọntun-wọnsi ni ki o ṣe lọsẹ yi, mase mu ọti pupọ, ki o si majẹun ni ajẹki ti o ba fẹ gbadun ara rẹ.

# Ijoba Fe Ge Owo Awon Osise Agba Ku Ni Nigeria

EKO—Bi a ti nfẹ lọ tẹ iwe-irohin wa yi ni alẹ ana, ni a ri iwe wosika kan gba lati ọdọ olofintoto wa kan wipe Ijọba Apapọse ilẹ Nigeria nfẹ ṣe ẹdinwoku fun awọn ọga iṣẹ Ijọba na laipẹ yi. Ọrọ na ki i ṣe lori awọn enia-dudu nikan; o kan awọn Oyinbo alawọfunfun paapa.

Owo ti nwọn fẹ ge ku na ko pọ pupọ. Onirohin Eleti-Ọfẹ ni ko ju sile-meji meji lori pọnun kọkan lọ. Nwọn ni owo-idẹra si irinajo ti awọn ti nfun awọn osise pẹlu awọn ọmọ ati iyawo wọn ko ni si mọ fun ẹnikẹni ti o ba jẹ wipe nilẹ yi ni nwọn f'ori rẹ sọlẹ si.

Ijọba ni o dabi ẹni wipe ireje wa ninu owo-ile mehaya ti awọn ọga-iṣẹ yi nsan fun ibiti nwọn ngbe ninu ile Ijọba, nitorina awọn ni lati joko jọ ṣe asaro lori ọrọ awọn owo ile na.

Ju gbogbo rẹ lọ, awọn ọmọ ẹgbẹ onisẹ-akọwe Nigeria ni gbogbo ibikibi ni Nigeria ti bẹrẹsi ṣe ipade ti wọn laye ọtọ lati ṣe alaye fun Ijọba nibi ti nwọn ba kuna lori ọrọ atata na.

# Ero Foto Okere Fun Radio



Aworan yi nl ti Ogbeni kan ti o nda ero yiya foto okere fun Redio ti awon Oyinbo onisowo Gesi kan sese se wo ni ilu London. Nwon ni ero foto yi se gbe kakiri fun lilo nibikibi, owo ti nwon si nta won ko po rara. Ti nwon ba se eto ero na tan ti nwon si nta a gbogbo awon ile-iwosan, akeko, ise-owo ati awon ile isere ni nwon a ma lo o fun aworan okere (Television) gbigba.

## E FOJU S'ONA

Ni ose ti mbo Ogbeni Onatade yio so itan awon Oyinbo Onisowo akoko fun nyin ninu itan "Eko Akete Ile Ogbon."

## ALHAJI TI O SESE DE NI

# Owo Ni Koko Ni Ilu Mẹka

### (Lati owo Alhaji Abudu, Ijebu-Ode)

Eko ba ti ri iwe irohin mi yi ka tipẹ, ṣugbọn wahala awọn ẹbi ati awọn ọrẹ ti nwọn nṣe aṣeyẹ fun wa nigbati a ti ti irin-ajo wa lati ilu Mẹka de ni ko jẹ. Ki aranṣẹ Anabi Mohamed (ikẹ ati Ọla ki o ma baa) ki o ma ba gbogbo yin gbe.

Ẹ jọwọ mo fi orukọ ojiṣẹ Ọlọrun na bẹ yin, ti ẹ ko ba ni owo lọwọ daradara, ki ẹ si tun ni alafia ki ẹ maṣe da'ba wipe ẹ fẹ lọ si Mẹka nitoripe gbogbo nkan ni ilu Mẹka ati Mẹdina ko si ọfẹ rara nibẹ, owo ni.

Mo niran ọjọ ti a kuro ni Ikẹja; gbogbo wa ti awọn Ọlọkọ-ofurufu ni ki a wa wọkọ ṣebi kiakia ni ọkọ na yio ṣi lọjọ na, ṣugbọn a ni lati sun ni ita ninu afẹfẹ bi awọn ṣọja ti awọn nko lọ si ibudo-ogun Kongo. Ọpọlọpọ awọn ẹlomiran ti nwọn ko sun lode - gbangba ri, lati Ikẹja ni nwọn ti bẹrẹsi sin lọ titi a fi de Kano.

Diẹ ni wahala ti Ikẹja nigbati a ri ti Kano, nitoripe awọn ogunlọgọ ero ni wọn ti pejọ si ebute Aropleni ibẹ ki awa to de. Bi enia ba ju abẹrẹ silẹ ori enia ni a bọ si. Enia pọ bi erupẹ ilẹ, Hausa ko jẹ ki a mọ awọn Yoruba, bẹsini awọn Yoruba ko jẹ ki a mọ awọn Hausa.

EBUTE JIDDA

Nigba gbogbo ni a ma ngbọ lẹnu awọn Musulumi miran, ti nwọn ko ni agbara lati rin irin-ajo yi, boya agbara ti owo tabi ti ara-lile ni, nwọn a si mura, nwọn a sọ wipe ilu Mẹka npe awọn. Iru Ogunlọgọ awọn enia bayi ni a kọ mba pade ni Kano ki a to wọ'kọ ofurufu lati ma ba irin-ajo wa lọ.

Mo ro wipe ni oru alẹ ọjọ kan, o to adọrin enia lọkurin, lobinrin, lọmọde ati lagba ti nwọn wa gunlẹ ni Kano. Mo bere lọwọ awọn oniṣẹ ọkọ-ofurufu ibẹ bi awọn enia na ṣeṣe nlọ si Mẹka tabi nwọn mbọ ni, nwọn sida mi lohun wipe awọn ara Nigeria ti nwọn ti tan si ilu Mẹka, ti nwọn ti lọ lati bi ọdun marun si mẹwa, ti nwọn kori owo-ọkọ lati pada si ile wọn mọ, ti Ijọba nko pada wa si ile ni wọn.

Iyoku di iregbe! ọkan ninu awọn Alahaji oni alọmọbọ yi, Obinrin Kanike, ara Bọrnu kan ti o l'oyun, bi ọmọ ninu ọkọ aropileni nigbati nwọn nwa wọn bọ wa sile. Awọn ọlọkọ alaropilemi na ti o gb'ẹbi fun un ni ofurufu si tọju Obinrin na ati ọmọ rẹ titi ti nwọn fi gunlẹ si Kano.

O ya mi lẹnu pupọ lati rii pe ọkọ aropileni kan ti nwọn npe ni Sabena le ko ero ti o to ọgọrun enia lẹkanṣoṣo. Ni oru alẹ ọjọ ti awa kuro ni Kano, awa mẹrindiladọrun (86) ni ero ti o ko lai ka awọn ti o nṣe iṣẹ ninu rẹ.

Ebute Jedda ibi pataki ti o jẹ fun ara Mẹka ti npe ilu wọn ni Saudi Arabia; nitoripe nibẹ ni gbogbo ero, ori-ilu kokan lorişirişi npejọ si. Wa ri awọn ti o wa lati ilu awọn Senegal, Morocco, Sudan, Sierra-Lone, Lybia, Gambia ati kakiri gbogbo agbaiye ti nwọn a pe sibẹ bamubamu.

Orişirişi owo ni nwọn si nparọ nibẹ. Mo ri owo miran ti nwọn ti nlo ki nwọn to bi iya-iya ti o bi ti o bi iya-iya mi pade nibẹ. Awọn Senegal nna owo-golu bi ẹniti o nna owo-kẹbọ lọhun ni. Bẹsini awọn alawọ-funfun miran ti o wa ṣe Hadji nibẹ.

Lọjọ ti o ba ti de Jẹdda yi ni iwọ alara paapa a ti mọ wipe o ni lati ṣe ọkan rẹ giri ki o ba Ọlọrun daniyan nkan ti o bawa ati pe ki o le pada sile pelu ori-rere. Lati Jẹdda yi ni wa ti gbe aṣọ-funfun rẹ ti nwọn npe ni Ihiran wọ ki ẹ to dori kọ ilu Mẹka.

Orun ilu Mẹka mu pupọ bi ina ni o ṣe njo enia lara, Ogunlọgọ enia ni oyi ngbe lulẹ ti nwọn nku patapata nibiti a gbe nlọ yi okuta Ka'aba ka lẹmeje. Ẹniti o ba ṣeşi şubu lulẹ oniyẹn ku patapata niyẹn nitoripe ibẹ ni nwọn yio tẹẹ pa si.

ỌMỌ-ITA MBẸ

Ko si ibiti ọmọ-ita ko si ni aiye, awọn ara ilu Mẹka na ni awọn ọmọ-ita ti wọn. nwọn si mọ ẹ'ṣẹ ebu ṣe daradara. Nwọn ni orukọ kan ti nwọn ma npe awa ajoji ni ilu na, nigbati mo bere itumọ rẹ lọwọ ẹnikan, o ni awọn ẹru baba awọn ni awa jẹ.

Ọrọ yi mu mi ronu pupọ, ṣugbọn nigbati o jẹ ọrọ ẹsin ni mo ba wa, ẹru Ọlọrun, ẹru Anabi Mohamadu (ikẹ ati ọla ki o ma baa) na ni awa Musulumi si njẹ pe ara wa.

Ilu Mẹka bi ilu Abẹokuta tabi apakan ni Ibadan ni o jọ, oke olokuta pọ kakiri ilu na, ile Ọba won si dara. Mo gbọ wipe beko ni ti Ọba wọn ati ... ni ojojumọ ni oju nlo si, nyẹn ni o jẹ ki Ọba ti nwa yi tun agbala tirẹ kọ ni ọna ti o ba oju mu daradara fun asiko ti a wa yi.

Mọto-ayọkẹlẹ ti o gbadun mbẹ ni Mẹka ati Mẹdina; bi awọn ọmọ oni-taksi ti wa l'Eko bẹnani nwọn wa jara ni Mẹka ṣugbọn iṣẹ wọn ko dabi alara ti gbogbo enia ti o wa si ibẹ ba ti gun Oke Arafa tan, ti olukuluku si pada si ilu won.

Ara mi, bi ẹ ba fẹ gun Oke Arafa, ki ẹ ni owo lọwọ, ki ẹ si jẹun, ki ẹ tokun ninu, nitoripe "Nitori Ọlọrun (laisi owo) kosi ni ilu Mẹka rara".

Abọ mi niyi o.


# OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA LE FI MA TA

BI IṢU AKARA GBIGBONA.

POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI—ỌFẸ

# ELETI–OFE

ANJUWON KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Koṣẹkọ Street, Lagos.    "ELETI OFẸ," LAGOS

P. O. Box 467    Phone 23370.

VOL XIV. No. 825. SATURDAY JUNE 23,- JUNE 29, 1962.


# O Ku Tiyin O, Alagba

INU wa dun lati gbọ wipe awọn alamojuto Ijọba Apapọse pa'ṣẹ wipe ki nwọn ṣe iwadi awọn ẹgbẹ–oṣiṣẹ ti nwọn mba Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe ajọṣepọ, ati pe awọn ti o ti jẹ opomulero Ijọba na (awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre) ni awọn paapa ko lodi si iwadi na ti nwọn fẹ ṣe rara, awọn si faramọ ọ, nitoripe gedengbe ni awọn wa, ko si kolokọlọ kan ninu iṣẹ ti awọn ṣe silẹ lati bi mefa tabi meje ti awọn ti di ijanu Ijọba Ipinlẹ na mu ki Ijọba gbogbo gboo to gba Ominira ni wọn nkan bi ọdun meji sẹhin.

Nitotọ, bi enia ba fi ọmọ–iṣẹ kan si ile itaja ti a si ko orisirisi ọja si itọju rẹ, o yẹ ki a ma bẹ iṣẹ ọwọ ọmọ–iṣẹ na wo lẹkọkan, ki on na mọ wipe bi on ba ṣi iṣẹ na ṣe awọn ọga kan wa ti nwọn le ba on wi.

Ti ọmọ–iṣẹ yi ko ba si fẹ itiju ati ẹgan, on na a si ma ṣe iṣẹ gbogbo ti nwọn ba fun ṣe daradara laisi ikunsinu nibẹ.

A fẹ ki ẹ mọ wipe gbogbo awọn ti ẹ fi idibo yan lati di opo Ijọba mu fun nyin, alagbaṣe yin ni nwọn jẹ, ko ba ṣe Ijọba Ipinlẹ Ariwa, Ila–Ọrun tabi Ijọba Apa–pọse nitorina igbakugba ni a le pe wọn wipe a fẹ yẹ iṣẹ–iriju wọn wo.

A tun fẹ ki ẹ mọ nkankan, iyẹn ni wipe awa Eleti-Ọfẹ a ko si nidi alabosi, idi otitọ ni a wa, nito–rina a bẹ awọn oṣelu wa ki nwọn jọwọ ki nwọn maṣe gba ọrọ Olotu wa ọṣẹ yi s'odi. Awọn ẹniti a ba fi alaye ọrọ wa ṣẹ, ki awọn jọwọ, ki nwọn darijin wa.

A bẹ awọn Olotu Ijọba Apapọse l'Eko wipe lẹhinti nwọn ba ti ṣe iwadi Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun tan, a fẹ ki Alhaji Tafawa Balewa ati Gomina–Agba Ọlọla Azi-kiwe ki nwọn paṣẹ wipe ki a lọ yẹ idi Ijọba Ipinlẹ Ariwa, Ipinlẹ Ila-Orun ati ti Ijọba Apapọse wo.

Ti nwọn ko ba le pa iru aṣẹ iwadi bayi fun awọn Ijọba Ipinlẹ yoku, a fẹ ki nwọn mọ daju wipe ifẹ ti awọn ara Nigeria ni si Ijọba wọn, ifẹ oju ni, nwọn ko fi inu tan wọn rara. Eleyi ni awọn Nigeria paapa a fi mọ awọn Ijọba ti o nṣe otitọ.

Otitọ ni yio leke.

# Iwe Si Olotu

## A Dupe Lowo Nyin

ADUPẸ lọwọ nyin pupọ, lori wahala yin ati igbe ti ẹ ba wa ke fun awọn alamojuto Ijọba wa, nipa ọrọ owo–tuntun ti ẹ sọ wipe ki nwọn jọwọ ki nwọn ba wa sun igba ti nwọn da wipe ki a ma ko awọn owo na wa siwaju, ti nwọn si ṣe bi a ti fẹ na.

Ọlọrun ki o pelu yin, ọkọ ọba ko ni ṣa yin lẹsẹ; ẹ jọwọ, ẹ tun bọ ma ba wa ṣe alagbawi wa na siwaju si ninu ohun gbogbo.

Emi ni,

Eko    T. Alabi

## A Nfe Ile Ipade Ni Ilu Awe

E jọwọ, olotu, ẹ gba mi laye ninu iwe irohin yin lati kesi awọn ọmọ ilu Awẹ lẹba Ọyọ wipe a nfẹ ki nwọn s'agbara lati kọ ile–ipade (town hall) si ilu na nitoripe oju ti la ju ki a ma fi ojojumọ pe si ita ka–kiri lọ.

O tilẹ yẹ ki ti ita-gbangba ti a npe ni "Ibọrisa" ti a ma npejọ si ma ti wa loju, nitoripe nigbagbogbo ni atẹgun ati ojo nma da wa lamu nibẹ ti a ba ti pejọ ti a bẹrẹsi ṣe ipade pataki. Nkan-ki-nkan ti a ba nṣe lọ-wọna, a ni lati da duro ni.

A bẹ awọn Oloye, awọn agba ilu pẹlu awọn ọmọde ati agbalagba, wa ki nwọn jọwọ, ki nwọn fi ọrọ na s'ero, ki a tete da da owo ki a fi kọ ile–ipade na fun ilọsiwaju ilu wa

Emi ni,

Eko    S. A. Bọlarinwa

## Ki A Mura Giri

Nisisiyi ti Dokita Majẹko-dunmi, Alabojuto Ijọba Ipin-lẹ Iwọ-Orun ti paṣẹ ti o si yan awọn mẹta kan wipe ki nwọn wa'di bi awọn Oloye Awọlọwọ ati Akintọla ti ṣe Ijọba Ipinlẹ na si ni akoko ti nwọn, a ṣe akiyesi wipe otitọ fẹ farahan nigbangba.

Ṣugbọn a dara pupọ ti nwọn ba le ṣe iwadi-ọrọ na ni gbangba, ki o ma jẹ ni ikọrọ ni nwọn a ti joko ro o.

Mo si tun da laba wipe gbara ti nwọn ba ti pari iwadi na, ki nwọn si paṣẹ lati ṣe iwadi awọn Ijọba Apapọse l'Eko ati ti awọn Ipilẹ miran nitori ominu nkọ wa si wọn.

Emi ni

ỌYỌ.    K. Alawiye

## Opa Agbeleka Tehin Loju

Awọn baba wa ni ilẹ Yoruba ni nwọn nma npa owe wipe, "bi Ọmọde ba ṣubu a wo iwaju, bi agbalagba ba ṣubu a wo ẹhin." Kini o fa sababi owe na ni ti gudugbẹ ti o n ja lulẹ lojojumọ ni arin awọn Oṣẹlu Nigeria. Oni a gbọ wipe nwọn fi iwe–aṣẹ–ihamọle fun lagbaja, ọla a gbọ wipe nwọn ni ki tamọdu gba igbo Irunmọlẹ lọ. Bi gbogbo ọrọ na ti nlọ kosi ẹniti ọ le fi ọwọ sọya wipe o ye on.

Ere ni, awada ni ọrọ na si fẹ bi Ige bi Adubi. Awa Eleti-Ọfe a bẹ gbogbo ẹnyin ara ilu ki ẹ ṣe suru, ki ẹ ṣe ọkan yin giri, ki ẹ si tun gbadura tọkan tọkan ki Ọlọrun le mu wa la iṣo-ro ti o wa ni iwaju wa na ja. Ki Ọlọrun ọba ogo pẹtu si ọrọ na, ki irẹpọ le wa larin wọn ni Ipinlẹ Ijọba Iwọ-Orun.

Ọpa Agbeleka Tẹhin loju o !

# Nihin Lohin Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

EGUN KO M'OKAN

Ninu ọsẹ ti o koja yi ni mo fi ẹsẹ kan de ilu Badagry ; boya ẹ le wipe nitori ki'nle ri ọti APẸTẸ-SI mu ni mo ṣe lọ sibẹ. Agbọdọ ! ọrẹ mi Ọba C.D. Akran ni mo lọ ki nitoripe nigbati nwọn ti fun ni iwe-ihamọle wipe ko "ma yoko, ko ma yodo", nko ti ri i, bẹ a si ti nṣẹ ọrẹ tipẹ. Ani nigbati o wa ni Lafiaji ni Opopo Lewis Street l'Eko.

Nigbati mo de ọdọ rẹ ni ilu Badagry, mo ba Segoa aya rẹ (ọmọ-bibinu Ologbe Branco) nibẹ ati Ọgbẹni wa ti o fi ọpa ile Igbimọ dabira ni Ibadan laipẹ yi ati ọpọlọpọ awọn ỌLẸ-TẸLE-ALUFA ti gbogbo wọn si nṣe aṣaro lori ẹgbẹ oṣelu tuntun kan ti nwọn ni Ọba Akran paapa fẹ dasilẹ.

O MBA WA Ṣ'ELU

Bi Segoa, Olori Ọba yi ti ngbe nkan jijẹ ka ori ina, ni o tun nsọ omiran kalẹ, ti nwọn si nṣe alejo pẹrẹwu. Mo wa bi nwọn lere wipe orukọ iru ewo ni nwọn fẹ sọ ẹgbẹ-oselu ti nwọn; nwọn ni 'EGUN KOM'ỌKAN'' ni o wu awọn lati sọ ọ. Ọrẹ mi apeja orukọ na ni EGUN KO M'ỌKAN, O MBA WA ṢE ILU. Mo ba wọn da ni imọran ki nwọn jẹ ki a sọ orukọ ẹgbẹ na ni ARIWODỌLA tabi Egun parapọ.

Nwọn ni awọn yio fi ọrọ na se'ro, ṣugbọn ki nto kuro nibẹ awọn Ọlẹ-tẹle-Alufa Ọba bere lọwọ mi boya emi na le ri aye ba awọn se 'kanpe' ni ilu Ẹgba l'Abẹokuta, nitoripe awọn ara wa wa ni Agọ-Egun nibẹ tabi ni Ibadan. Awọn ko fẹ ẹgbẹ Ọlọmọlangidi o.

Enu-ofifo kii dun namu-namu; ti nwọn ba ti le ba mi wa owo diẹ ki nfi si apo pẹlu igo EGUN-KO KỌ-KAN mefa ki nfi su're, ki nwọn dami-da'yoku. Emi na nfẹ oye-ranpẹ ninu ẹgbẹ na, nitori ki oju mi le maa to gbogbo nkan ti a ba fẹ pin ninu owo-ẹgbẹ.

DO, BURADA!

Nkan ti ko jẹ ki nle lọ si ọdọ ọrẹ mi Alhaji Sule Gbadamọsi ninu ile ẹlẹha-ọkunrin ti Ijọba fi si ni Warri ni pe kosi ijoko ti a o fi joko ati awo-ọbẹ ti a le fi jẹun; gbogbo rẹ ni awọn "Obo-adori" ti gbe lọ patapata. Warri ni o ni Wayo, Wayo ni o ni Warri. Mo tilẹ tun gbọ wipe awọn alejo-oru na tun de ibi ti nwọn "ha" Ọgbẹni Alfred Rewane si. O maṣe o, iya njẹ ọmọ-onile!

Alfred, do o! O dojumọ o, Oriṣa a gbẹbẹ rẹ o! Itsẹkiri ni mo fẹ yen o. Bi ko ba ye yin ki ẹ lọ wo iwe-ede (Dictionary) OMIMI-EJO tabi ki ẹ lọ si Ọbalende, nko sọ wipe ki ẹ lọ si Ajegunlọ nitoripe awọn OBO-ADORI ni o pọ nibẹ, ọta-ko-gbẹbọ ni wọn pẹlu awọn "Do, Burada."

SAN-DIẸ-DIẸ

Ni aiye atijọ awọn Ijẹsha ni nwọn ma nṣe iṣẹ 'OṢO-MALO-gbowo-mi', ṣugbọn nisisiyi awọn Oyinbo onişowo paapa ti nṣe iṣẹ yi, (nwọn si npe orukọ ti wọn ni H. P. Hire Purchase). Mo gbọ wipe gbogbo awọn oṣelu ẹlẹha, ti nwọn ha mọle, ti nwọn ra mọto-ayọkẹlẹ ati firigi (ile omi-tutu) ni awin lọwọ awọn 'Oṣo-malo' Oyinbo yi ni nwọn ti lọ gba awọn mọto na ati ẹru wọn lọwọ wọn. Nwọn ni ibiti iyawo alarede kan gbe ngun mọto tirẹ lọ ni nwọn gba lọwọ rẹ ni Oke-Ado ni Ibadan ni ijẹta. Mo gbọ wipe ọpọlọpọ awọn Oyinbo ti nwọn mba awọn oṣelu wa kọ ile GOGORO ni nwọn ti da ọwọ ile kikọ wọn na duro nigbati rogbodiyan ti bẹ silẹ nitoripe nwọn ri wipe owo san-diẹ-diẹ ti awọn ngba fun ile kikọ na ko le bọ si awọn lọwọ daradara mọ.

Emi Ayiluka mọ iwọn ara mi ni mo ṣe nwọ mọto-bọlekaja kakiri ilu. Mo mọ iwọn ara mi ni mo ṣe nmu tii (tea) lai fi ṣuga sii nitoripe emi ko le ṣe ogun jẹdijẹdi.

ẸLẸHA ỌSAN GAN-GAN

Mo ṣẹṣẹ nmura lati lọ ki Baba ni Ikẹnnẹ (Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni o njẹ bẹ) lati lọ ba ṣe ọjọ Jimọ ana, ni mo gbọ wipe Dokita Majẹkodunmi, Alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti tun haa ni iwe-ihamọ miran, on ati Baba Ogbomọsho Oloye Akintọla. Nwọn ni ki Awolọwọ lọ fi ara pamọ si eti okun Lekki ni Ẹpẹ ati pe ki Oloye Akintọla lọ si igbo Olokemeji leti oko baba mi lẹba Odo Ogun.

Ko si nkan ti o dun mi ju ọkọ oju-omi ti nko ni lọwọ lati fi sọda lọ ba Oloye Awolọwọ jẹ ẹja ọbọkun Ẹpẹ ati Kuta olodo. O si tun dun wipe akoko ti Oloye Akintọla lọ si Olokemeji ko bọ simu ẹrun, ẹran-igbẹ ni Ẹmili ko ba ma fi da'la. Ṣugbọn sibẹ-sibẹ mo jẹri awọn ara Eruwa, nwọn a mu eran-igbẹ ati elubọ wa fun un. Ọrẹ mi Ọgbẹni Adedeji ("Baba Lẹjẹ") wa nibẹ, a si ṣe gbogbo eto, mo fi iyoku le e lọwọ. Mo tilẹ gbọ wipe Baba Ogbomọshọ paapa tilẹ ti yan oye fun "Baba Lẹjẹ" ninu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti o ṣẹṣẹ fẹ dasilẹ.

Ẹ o tun ma gbọ iyoku lọsẹ ti mbọ, kiisu u, kiirẹ ẹ ni ọrọ Ayiluka.


## E kilo fun omo yin




**Kiwon mase fi omi sere**

## Owo Olopa Te Baba Ti O Pa Omo Re

ONDO— Laipẹ yi ni awọn Ọlọpa Ondo lọ mu ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Emanu Fasoranti ni Ododibo wipe awọn fura sii pe on ni o pa ọmọ rẹ ọkunrin ti o ku ni airọ(?)i.

Awọn Ọlọpa ni iyawo ọkunrin na, Florence Fasoranti, ti o b ọmọ na, sọ fun awọn wipe ọkọ on ni o dan ogun b-kuku kan wo lara ọmọ na, ti o si paa.

Iyawo rẹ na ni, o ti pẹ ti ọkọ on ti nwa ogun a-jẹ-bi ina kiri lati lo fun ẹnikan ninu awọn ọrẹ rẹ ti o ti ni ija rẹ si'nu. O ni, onişegun ti o fun ni egbogi na ni ki o danwo lara ewurẹ, şugbọn lara ọmọ on ni o danwo. O ni ọkọ on ti jẹwọ fun on wipe egbogi na pa ewurẹ meji ti on kọkọ lo fun ki on to wa lo fun ọmọ ti o ku na.

Awọn Ọlọpa si nwa baba onişegun ti o fun ni egbogi na kiri.

## E Ma Ka Ayiluka Fun Irohin Aladun

Awọn òwò sise tuntun ni ijẹri si ilọsiwaju

UAC

nran awọn ọmọ Nigeria lọwọ lati di onişowo asiko ati lati da duro fun rawọn

O le ni igba (200) ọmọ Nigeria ti o wa ninu işe atunta eja tu tu ati ohun jijẹ miran ti nwọn si nfi ẹro refrigerator to ju nwon pelu iranlọwo lati ọdọ U.A.C. ati anwọn onişowo ẹlẹgbẹ nwọn.

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

## A B D NI ELETI-OFE

(Lati ọwọ J. Ọla. Wins)

E Epe pọ ju nkan ti o nu lọ, abẹrẹ sọnu a gbe şẹrẹ, ari abẹrẹ tan, şango gba'gbo.

L Lukoye la'lukoso elenpe, ẹyinlẹ ni t'orişa, ajala ijidun ni ti Şango, olubirọ ni talakẹdun.

E Eyi ara! a di gari silẹ ewurẹ yọju, i şe ẹru agutan baba rẹ ni?.

T Tẹtẹpopo gbonde l'ọrun, onikaluku a bi tirẹ lara.

I Igbẹ adiẹ ko dara ni Mọşala i, şugbọn itan rẹ dara lori irẹsi fun Alufa.

Ọ Ọmọde jogun ile o nyọ şẹşẹ, o gbọn to baba rẹ to kọọ?

F Fi oni ku, fi ọla ji, ọjọ kan nii ku tan patapata.

Ẹ Ẹni ti kọla (collar) yun lọrnn sanju ẹniti lgi'i ya pa lọ; ẹniti bata ba ge lẹsẹ san ju ẹniti jiga ge lẹsẹ lọ.

## Ijoba Amerika Tun Ya Nigeria L'owo

WAŞHNIGON—Awọn Olotu Ijọba ilu Amerika ni awọn ti f'ọwọ si iwe kan ti awọn fẹ fi ya awọn ara Nigeria ni £714,000, lati fi kọ ile asọ-hihun si ilu Aba ni Ipinlẹ Ijọba Ila-orun.

Nwọn ni ti nwọn ba kọ ile işẹ na tan ẹgbẹrun awọn ọmọ Nigeria ti ko ri işẹ şe ni awọn a gb a si ibẹ, ti awọn yio si ma kọ bi nwọn şe nran owu aşọ, bi nwọn nşe pa aşọ laro ati orişirişi işẹ aşọ-hihun.

Nwọn ni ti a ba ti mu ẹrọ asọ-hihun na ti awọn yio m wa lati ilu Amẹrika kuro, nwọn ni awọn ohun ija işẹ na ti o ku, Nigeria ni nwọn yio ti ma ri wọn.

## Ghana Politics:

# "Jaja Does Not Know.."

## Western Region Crisis Recalled

### (By our Accra Correspondent)

ACCRA—Recent Press controversy between Nigeria and Ghana on the subject of Ghana resorting to subversive activities in Nigeria is still a daily discussion among the people. Quite a lot of Ghanaian writers have written many articles in local Press to attack our system of goverment and our Minister of Foreign Affairs, Mr Jaja Wachuku. One says he does not know ins and out of politics, another writes that "his behaviour is very disappointing at times.

### To Wachuku

One E.N. Odonkor, Vice-chairman of Tema branch of the Convention People's Party writes an open letter to Mr. Wachuku:

"DEAR Wachuku,

I do not think you know the ins and out of politics. As such, you should hold up your lips and learn something from Ghana politics. Our leaders in Ghana, know the masses and they in turn know them.

"By now, I think you have learnt something from Mr. Tawia Adamafio, our Minister of Information had Broadcasting, when he held a press conference to expose your anti-nationalist ideas to the reading public.

"To remind you, our Government is not fighting for herself alone but for the whole of the African Continent. This you can trace from the many African Conferences held here. It is unity from the deliberations of purpose that Ghana is after. Nothing more and nothing less.

"If you aspire to be the Leader in Nigeria, I will advise you to take a political course in the Kwame Nkrumah Ideological Institute at Winneba where the A.B.C. of politics will be taught you.

"I say again, Mr Jaja Wachuku, leave Ghana alone and stop that nonsense."

### West Crisis Recalled

MR. Kwesi Armah, Ghana High Commissioner in London in one of his dispatches mentioned the recent crisis in the Western Region of Nigeria and says that "Ghana sympathises with the crisis in the Western Region of Nigeria. We hope that it will be temporary and that a quick settlement will be reached which will be supported by all the leaders and people concerned.

"We hope that it will be possible for a party of Ghanaian pressmen to visit the country so that they may understand from first hand knowledge the problem and progress there.

Another writer asks, "may I know from our Nigerian friends whether Ghanaians trading in Nigeria are given fair treatment?

"In the Armed Forces, the Police, the Civil Service we have Nigerians in high executive posts and we do not discriminate on tribal grounds. Africans and people of African descent work among us and get the same facilities as Ghanaians. Will our Nigerian friends confirm that the same fair treatment is given to Ghanaians in Nigeria?

### Prefabricated Houses Being Sent To Nigeria

NEW YORK — Six prefabricated houses – four wooden and two aluminum-are on their way to Nigeria, the first commercial shipment of its kind from the United states.

Supervisors from the manufacturing Company, Gold Star Homes, Inc., will assemble the houses in Nigeria.

Each four-room house has electrical wiring, Kitchen fixtures and cabinets and all other items normally built into a home.

The houses are being shipped on the Farrell Line's ship "African Sun"

## ROYAL BIRTHDAY



Members of the British Royal family (including the Queen herself in centre) gather on the balcony at Buckingham Palace, London after the Trooping the Colour parade to mark the Queen's official Birthday which was held recently.

# Coker Sun Ojo Iwadi Awon Egbe

## Alabase Ijoba Iwo Orun Siwaju

EKO —Gbogpo ẹṣẹ awọn oniwe irohin, awọn lọya pataki pataki ati awọn ara ilu ni o pe si ile Igbimọ-nla (Senate Building) lati gbọ ọrọ iwadi awọn ẹgbẹ alabaṣepọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti Dokita Majẹkodunmi, Alamojuto Ijọba ipinlẹ na paṣẹ wipe ki Adajọ G. B. A. Coker pẹlu awọn oluranlọwọ meji ṣe iwadi.

KO SI ỌDARAN

Nigbati awọn oluwadi na pade ninu ojo ni owurọ ijẹta, Adajọ Coker, tiṣe alaga iwadi na ni o sọrọ. O ni iwadi ti awọn fẹ ṣe na, idi otitọ ni awọn fẹ wa, awọn ko sọ wipe ẹnikan ni o SAN EGUNGUN TI NWỌN SỌ MỌ AJA LORUN. Awọn si fẹ ki gbogbo awọn onIwe irohin jakejado pa ẹnu wọn mọ, ki nwọn maṣe kọ ọrọ buruku tabi yinyin ẹnikan nipa ọrọ na ti awọn vi'o ti ṣe iwadi na tan.

O ni on a sa gbogbo agbara on lati ri wipe gbogbo awọn ti nwọn ha ni iwe-ihamọ, ti nwọn si fi ara pa ninu ọrọ iwadi na, wa si ile lati wa sọ ti ẹnu wọn; o tun ṣe alaye wipe on ko fẹ ki (rọ iwadi na ba awọn lọya olukuluku ti nwọn yio sọrọ nibi iwadi na labo, nitorina on fun wọn ni ọsẹ mẹta gbako, ki nwọn fi lọ palẹmọ ọrọ wọn.

Adajọ Coker ni kiṣe li Eko nikan ni awọn yio ṣe iwadi na nigbati awọn ba bẹrẹ ni ọjọ kọkanla ọsu ti mbọ, awọn ni lati lọ si Ibadan ati ibomiran pẹlu.

# Raphel Gun Mope Lo'be

EKO — Bi o lọ k i o yago lọna n i gbogbo awọn ara Ẹpẹtẹdo ṣe nsare sihin ṣọhun nigbati nwọn ri ọkunrin kan, Raphel Ọlabanjo ti o fi ada igudan ge obinrin kan, Mopelọla Ayinde, ni ọrun-ọ w ọ kalẹ ni agbo-ile kan ti nwọn pe ni Agbo-Malu Court ni alẹ ijẹrin.

A ko ti mọ nkan ti o fa sababi ọrọ na.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Compay, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; OLOTU: OLA. ONATADE, 15, Kosoko St., Lagos.

# Ajao Ku

ANU ṣe awa oniwe irohin "Eleti—Ọfẹ lati tu ọfọ Oloye Joseph Adediran Ajao (ẹniti adape oruko rẹ njẹ ẸFUJE) Ọtun Ọyọ, Balogun ilu Awẹ ti o jalaisi ni Eko ni oru ijẹta Alamisi, ẹni ọdun mẹjilelogota ni, awọn ọmọ-bibi inu rẹ ti o fi s'aiye lẹ ni ogun.

Ọkan ninu awọn ọmọ Ologbe na ni Olori Ẹyesọrun Ọba Deji Akurẹ ti on ati Ọba na gb'atẹgun lọ si ilu Oyinbo laipẹ yi. Bi nwọn ti de ebute Liverpool ti nwọn fẹ wọ ọkọ oju-omi APAPA pada bọ wa si ile ni nwọn ri waya gba wipe baba Olori Ọba na ku, ni nwọn ba palẹ ẹru wọn mọ ni werewere kuro ninu ọkọ na ti nwọn si lọ wọ'kọ ofurufu.



Ọba Deji ati Olori rẹ na si ti gunlẹ si Ikeja ni ọsan ana. Ẹ o ri wọn ni ibi oku na ni ọsan oni. Bi ko ba si ti awọn Oyinbo Gẹsi ti o gba wọn ni alejo, ti nwọn se'to ọkọ orurufu ni o ni kiakia ni, ni Saro ni nwọn ko ba ti tufọ Ologbe na fun wọn ninu ọkọ loni Satide.

Ni igba aiye Ologbe na, o jẹ ọkan ninu awọn oguna-gbongbo ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ( AG ), o si nawo na'ra sinu ẹgbẹ na pẹlu Ẹgbẹ ọmọ Oduduwa.

Ni ọjọrọ oni Satide ni nwọn yio sin'ku rẹ l'Eko lẹhin ti nwọn ba ti gbe e lọ si Ṣọsi awọn Onitẹbọmi (First Baptist Church) ni Broad Street.

A ki ẹnyin ọmọloku, ẹ kuaṣẹhinde.